# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. II. NOS. 98 & 99. SATURDAY, MAY 24 & 31, 1924. 4d.

**DURO THOMAS.**

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO **J. F. SICK**

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirişi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita:—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumădan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa; Awọn nkan wọnyi fun tita:—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Àjàrà (*Wine*), Awọn onjẹ Ipanu, aşọ iş'ọşọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni:— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ẹkọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ Iorişirişi lati adọta ọdun ṣẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awon onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

**What a wonderful Medicine is this ?**

IS IT MAGIC?

D. A. Thompson, Licensed Herbalist has just received these from Ṣaki and Bariba to cure any complaints brought to him viz :—Iko fe e, Warapa, Aşiwere, Ọlọ Inu, Pakunpo, Wodi-wodi, Atoriwa, Jakutẹ, Oju ti o yọ owo, Jẹdi-jẹdi, with assorted medicines suitable for barren women. Children's treatment and assorted Agunmu in bottles in the shop for sale.

*The proof of pudding is in the taste*

Come and have a trial

No. 2, AROLOYA STREET, LAGOS.

Cable Address :—
"Steinafrik" HAMBURG.

**E. H. STEIN & Co.**

HAMBURG, Neurwall 16/18.
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

*ALL INDENTS EXECUTED.*
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

---

ẸNIKEJI,

Aṣọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, I Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

---

# CONGOLEUM SQUARES.

## THE LATEST IN FLOOR COVERINGS.

We have been appointed Sole Agents for Nigeria for CONGOLEUM SQUARES, and can thoroughly recommend them on account of their splendid wearing qualities, and also because of the cheapness in price. They are especially suitable for cement floors.

They are easy to keep clean, but hard to wear out, unaffected by dampness, moisture, insects, rot-proof, and strictly sanitary.

We hold a stock in a good range of patterns, and various sizes from 6 feet by 6 feet, to 15 feet by 9 feet.—

*We invite you to come and inspect same at :—*

JOHN WALKDEN & CO. LTD.,
MARINA, LAGOS.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—:o:—

ẸNI TO BA DAKẸ T'ARA RẸ A BA DAKẸ.

Ko dẽde ti a ko fi tẹ *Eko Akete* ti Satide to kọja s'ode, nigbati a sin pupọ ninu awọn ẹni wa ti nwọn ngba Iwe-irohin na ni owo ti nwọn jẹ wa fun gbigba iwe na, ti ko si lori ti ko ndi: nigbati a si wo ọtun, ti a w'osi ti o dabi ẹnipe irantọwọ pin, n'gbati a si f'oju sun inira ti irufẹ air'owogba bẹ lati mu ba iṣẹ na lọ yio mu wa, lọ fi jẹ ki a da iwe ti ọsẹ to kọja duro; o dun ni pupọ fun ọgọrọ awọn enia wa ti nwọn ti sanwo silẹ, ṣugbọn ti ireti wọn lati ri gba lasiko di omulẹ m lo, a si bẹ wọn gidigidi pe airi owo to lati ma ba iṣẹ na lọ nkọ wa l'ominu gidigidi.

Boya awọn ẹlomiran le wipe kiniṣe ti aroye tiwa lọna yi fi pọ bẹ ati pe awọn Iwe-irohin miran ki nsaba ma ṣaroye; nsi ti a le fun irufẹ ẹni to ba ni ero yi ninu ni pe Ekinni owe ti a le pa niti meji tabi mẹta nipa awọn Iwe-irohin miran ni pe Ohun ti agbalagba fi nje'kọ, abẹ ewe lo wa. Owe keji si ni pe O ni ohun ti o nlu fun iremi jo; Akere-mọ'do ko ṣai ni baba ni'salẹ; ṣugbọn olukuluku lo mọ ibiti bata nta on lẹsẹ lọna bavi.

Ẹnyin Ilu, bi ọrọ na ti ri n yen, ki iṣe ifẹ inu wa lẹjọ kan ati abọ l ti da ẹnikẹni loro fun airi *Eko Akete* ka lọsọsẹ a si dupẹ lọpọlọpọ fun awọn ti nwọn bere idi rẹ ti a fi da iwe na duro lojiji bẹ lọsẹ to kọja; ṣugbọn nigbati ko ba si loju, ki lo ma kan s'aiya o? N torina ilọsiwaju *Eko Akete* d'ọwọ ẹnyin Ilu, ẹnyin la ri ki a to ṣi'gun, ẹ jọwọ ẹ maṣe jẹ'ye Afunfere bikoṣe oye Jagun-jagun ko ṣe f'Ọba nu! Jagun-jagun ko ṣe f'Ọba nu!!!.

Yio dara fun gbogbo wa kari-kari, Aṣọ.

"ỌBẸ" LỌRUN SỌNNI DẸNGẸ, ALAO ATI ALAWẸ.

Ẹjọ Apania la fi pari Ile Ẹjọ awọn *Jury* ni *Thursday* ọsẹ to kọja, nigbati awọn *Jury* ti a ti pe lati gbọ ẹjọ na fun ọjọ mẹrin tọtọ wa'riko nighẹhin-gbẹhin, nwọn si fi ohun ṣọkan pe awọn enia mẹta na Sọnni Dẹngẹ, Snumọnu Alao, ati Akitọla Alawẹ jẹbi iku fun dide'na ti nwọn de'na de awọn ọkọ ero ọja ti nlọ si Ejinrin ni ọjọ 17 oṣu *February* to kọja lọna Orepete ati Oriba, ti nwọn si pa awọn mẹfa tan ninu ọkọ na; Adele Adajọ Agba si da wọn lẹbi iku; ki a to ri ọsẹ meji si awọn Apania wọnyi yio ti yọ s'ọrun ọsan gangan, nipa yiyẹgi fun wọn. E-pà-rì-pà! Baba ṣọ ni!

AJINDE ARA A MA JẸ FUN NYIN O, ALHAJI AKEWU-ṢỌLA.

A gbọ pe o fẹ diẹ si Alhaji Abudu Ramọnu Davies ti Ita Martin ni lọlọ yi ṣugbọn a ṣọpẹ gidigidi pe ilọra na ti nfuyẹ lọpọlọpọ; Ọpo kekere kọ ni Alhaji wa yi jẹ ni igboro ilẹ yi, papa larin awọn Janmia Musulumi, ẹrin ọyàyà rẹ ni ko to da ẹnikẹni lara ya ni, tabi iwa pẹsẹ ati ibanikẹdun rẹ? Ki Baba tubọ s'ẹmi rẹ siwaju fun wa ati ẹmi awọn jakanjakan miran ninu awọn Musulumi bi :—

Bakare Minsinun, Sanni Shitta Bey, Abibu Oki Balogun, Mọgaji Mumuni Animaṣaun, Alhaji Sanni, Kasunmu Avọrinde, Abudu Ramọnu Aranmọletiẹṣọ, Alli Balogun, Abudu Ramọnu Olori, Lemọmu Ligali, Brimah Igbo, Kasunmu Gbajabiamila Basọrun, Sanni Kekereogun, Karimu Kọtun, Abasi Ẹlẹgba, Alli Ọbanibaṣiri, Yesufu Agoro, Sanni Adewale,

Belo Arọwasi, Belo Alufa, Adamu Animaṣaun ati gbogbo awọn Janma to ku patapata l'ọkọnrin l'obinrin a ko fi oju fo ẹnikọkan da ati awa Kiriyo na pẹlu.

A si tun ki Alhaji Davies ku af'ojubà aburo rẹ Alhaji Ismaila to de lati *Port-Har-Court* ni lọlọyi.

### AṢEYI Ṣ'AMỌDUN.

A ki Akinlolu Akodu Ọlọtọ titun, ati awọn ẹbi rẹ ku inawo ọdun Agbá ti nwọn ṣe lẹnu ọsẹ to kọja gẹgẹ bi pupọ enia ti mọ; ojo ki ṣai rọ fun ṣiṣe ọdun yi, eyi to si rọ lẹnu ọjọ diẹ ṣẹhin tu ẹnikẹni lara. Njẹ ẹnyin ara wa, ã ri ọpọlọpọ ede jẹ o, ati iga akan gbe ṣere !!!

### L. KASUMU AROWO-ṢEFUJA, YIO DARA.

A gbọ pe ọrẹ wa L. Kasumu fi iṣẹ silẹ lọdọ awọn Oyinbo *African Association* ni lọlọyi: nigbati a wadi rẹ a ri pe owo ti wọn nsan fun ni ko to: awọn Oyinbo na si ka ọja wọn o si pe perepere; nwọn si da owo ti ọrẹ wa na fi duro lọdọ wọn pada fun u, ko si jẹ ẹnikẹni ni kọbọ. A bã yọ. Oluwa yio pese anfani.

Ọrẹ wa yi npete laipẹ lati lọ "foju kan Ọba" ni Ilu Oyinbo pẹlu Iyawo rẹ Miss Taylor. Eyi wu wa o.

### MOTỌ NPA BI MA PA NI IBADAN—IGI DA.

Ojiji la gbọ iku Ọgbẹni Charles L. Ọdẹbiyi ti Mọto kan pa ni Ibadan ni apafọn lọjọ *Empire Day* to kọja bi on ati awọn ọrẹ diẹ ti nti Ikarẹ bọ fun Ekurọ-rira: Motọ ti wọn wọ gbokiti-ọbọ o si tẹ Ọgbẹni na rẹ o si fọ lẹnu tutu: ko pẹ ti Ọgbẹni yi wa s'Eko pẹlu Professor Oyerinde fun Ipade Ajọdun Ṣọṣi wọn (Alaribomi). A tilẹ ri i nile Alufa J. R. Williams to fi ba ni jẹwọ-jẹwọ. A gbọ pe a sin oku rẹ ni agogo mẹrin ọjọ kanna. A ba awọn ẹbi rẹ kẹdun atẹhinku yi.

### PIPE LA NPE GBỌN, A KI NPE GỌ.

O jẹ ohun to dun ni lati tun gbọ pe alamọri ọrọ a sami a-ko sami fun awọn ọmọ ti a ko gbe iya wọn niyawo ni Ṣọṣi—ti awọn ẹlomiran ninu awọn to npe ara wọn ni Onigbagbọ nfi funfun pe dudu ti nwọn si nfi dudu pe funfun—nipa pipe Ofin Igbeyawo ni ọna Gẹsi ni Ofin Kristi—fẹrẹ da rugudu silẹ ninu Ajọdun (*Synod*) ti awọn *Church* C.M.S. ṣe ni ilẹ yi ni lọlọ yi: a tilẹ gbọ pe *Bishop* Olori wọn gba ọrọ na sodi tobẹgẹ ti a fi sọ fun ni pe, o ni ti ko ba ṣe ṣe, on le fi iṣẹ silẹ nitori ọro na—bẹ la gbọ, a ko mọ bi otitọ ni tabi bẹkọ—nigbati a sọ pe diẹ ninu awọn Alufa sọ ti iṣoro ti nwọn nba pade lẹnu iṣẹ wọn ni 'lu oke nitori ọrọ yi. Loju wa, ko yẹ ki ọrọ nkan l'asan, nkan aiye bi Arede—ti awọn ẹlẹwọ miran npe ni Arede, Apala—jẹ ohun idina tian-tian ti yio fi da Ijọ Enia Ọlọrun ru larin awọn *Church* C.M.S. ni gbẹgbẹlẹ yi: ki a tilẹ da silẹ k' a ṣa, Arede melo ni Kirsti tilẹ gbe lode aiye gidi, ti a ko jẹ ki enia mi? Họwu! Kini 'un na, kini kẹtẹkẹtẹ lara kẹtẹkẹtẹ, a-gun-fẹsẹ-wọlẹ? A ti sọ titi ohun wa fẹrẹ ha pe Igbeyawo ko ni nkankan ṣe pẹlu sisin Ọlọrun ni ẹmi ati ni otitọ: Ẹ gbọ bi orin kan ti wi.

O ba f' Okun wẹ 'ri o,
O ba f' Ọsa wẹ 'sẹ o,
Ẹni Jesu wẹ lo mọ tọkan-tara.

Njẹ, ki a ma ṣe ti oju aiye nipa gbigbe obinrin kan niyawo ni *Church*, ṣugbọn ki a ma lọ kubẹkubẹ lati ba-ti awọn "Ọmọ-ẹiyẹle" miran ti a ti fi ha si ibaba, si ikọkọ, kakiri igboro ti a o si ma "ron-gadi" (*run guard*): lọdọ wọn lalalẹ lati adugbo kan de keji, lalai ṣe Ọlọpa 'nu, ṣe aṣa yi ni ohun kan gumo ti o si tọ suna loju Church? Ẹnyin Olori-Afa, Ẹnyin Alufa, Ẹnyin isọri-isọri gbogbo Ijọ C.M.S. ti apa iha ihin, o d' ọwọ nyin o: Kini, Ẹ ti yara gbagbe ọrọ iyebiye ti Jesu sọ niyẹn? Ẹ tun gbọ, "Nitoripe, li ajinde oku, nwọn ki gbeyawo, a ki si fi wọn funni ni igbeyawo, ṣugbọn nwọn dabi awọn Angẹli Ọlọrun li ọrun."—*Matt. 22, 30.* Ẹ ma mọ itumọ eyi sinu larin nyin: iba Owo ti a ni, ni a ya nyin yi.


## Beer! Beer! Beer!

*We have just received a consignment of our celebrated:—*

**"ELEPHANT" BRAND LAGER BEER.**

*APPLY TO:—*

**JOHN WALKDEN & CO., LTD.,**
MARINA, LAGOS.

For price etc.,

## FAMOUS SOAP FACTORY.

### A Boon to Nigeria.

*By the Editor.*

The advent to this country of the West African Soap Company Limited at Apapa a Company Associated with the well known house of Lever Brothers Limited of Port Sunlight fame, England marks another epoch in the commercial advancement of this great Dependency.

We were priviledged a few days ago to meet the representative of the firm who was good enough to explain to us the activities of the great soap manufacturing firm as well as the *personnel* of the establishment. Of the former the soaps which will be turned out at Apapa will compare just as favourable with those of similar quality generally exported from England and the pleasing feature of the arrangement such as this is that several distinct brands of soap are being introduced for the Nigerian Trade which include NEPTUNE, BUGLE, and JOCKEY, for Pale and yellow soaps, and MAGNET brand for Carbolic quality.

That there is sure to be a ready market for this commodity once it is brought to the knowledge of our people both here and elsewhere goes without saying as the advantage which a venture such as this offers to tradespeople is that it will enable them to secure their wants in this direction at their very door to say nothing of the business relationship which we are positive is bound to follow in the long run, between the manufacturers and buyers.

Of the latter we make bold to say that the business could not be left in the hands of better men than Mr. Griff. Williams the Managing Director who arrived here from England by a recent mail boat. Mr. Williams has travelled extensively in the interests of the Parent Company and credited with many years experience behind him.

Mr. W. H. Ward the Accountant, Messrs Evison and Gandy, Works Manager and Soap Maker respectively, and two Salesmen who are now on tour in Nigeria ... other West African Colonies.

We learn also that this Establishment at Apapa provides work for many of our kith and kin, who are taught this useful, healthy, and non-offensive industry and, if for no other reason, we cannot but congratulate ourselves in being fortunate in having in our midst at the present time, some European business friends, who, quite apart from any profit making considerations, take delight in teaching our people one of the handicrafts which have made and is still making the ancient and historic house of Lever Brothers well known through out the world.

"THE WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA," have our good wishes for a successful career.

---

## OLD GRAMMARIANS' SOCIETY.

### Annual Dinner and Founders' Day.

Members of the Society who desire to attend the Annual Dinner on June 5, should please notify the General Secretary, Folamobi House, Lagos, before June 2.


## AKANṢE TITUN.

### IRIN DIAMOND ẸLẸMU.

Kere o ! Kere o ! !

A fẹ sọ fun ẹnyin ara ilu pe a ṣẹṣẹ ni Irin titun Ẹlẹmu ti o npọn ọbẹ daradara, o si wulo pupọ fun awọn Agbẹ; Irin Ẹlẹfufu ni a fi ṣe, o si npọn Ọbẹ, ati Ake bi da-nga: t'ewe t'agba lo nyọ mọ irin yi ṣẹṣẹ, a si ti nlo ni ilu Lome.

Awa nikan ni a ṣe Irin *Diamond* yi fun, awa nikan lo si nta a ni *Nigeria.*

Ṣile kọkan pere ni, a o din ẹniti o ba fẹ ra pupọ li owo. Ẹ wa ke si wa.

**N. V. Handelmattschappij V.H.**

Oyinbo J. F. SICK.

Ọba Ilẹkẹ

ni 5, Ibode lailai,

Eko.


---


## Ero ya wa ra.

ADEBOYE ṢOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Iṣọ lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun a ti Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.


---

Ti ẹ ba ndahun Ipolowo-ọja inu Iwe-irohin yi, Ẹ jare, Ẹ ma şai sọ pe inu "*Eko Akete*" lẹti ri ka.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, MAY 24 & 31, 1924.

## AIYA ILU EKO MBALẸ BỌ. A YIN OLUWA.

Lati iwọn oșu melo sẹhin, ko si ẹniti ko mọ pe gbemi s'oke gbemi s'odo, ati hilahilo, b'o ba o mu, b'o ba o bū l'ẹsẹ ti o ti wọpọ nibi ri ni igba kan șẹ nkasẹ diẹdiẹ, tobẹ ti a le fẹrẹ tilẹ sọ pe rugudu kan ko si ni igboro ilẹ yi ri; bẹ lo ri, ori ni gbogbo nkan, ẹ ko gbọ bi owe wa kan ti wi :—"M'ori lọ ma m'ẹwa lọ, ðjọ l'ẹwa mbọ, ori lo nba ni gbe'le ọkọ." Kosi igbati Oloye Sir Donald Cameron K.B.E. Șẹkiṭẹri Igbakeji Ọba, ti o jẹ Adele Gomina nisinsinyi ma bọ si ipo ẹniti o nko *Nigeria* ni ijanu lẹhin igbati Gomina Agba Sir Hugh Clifford ko ba si ni'le, ti a ko nri isami rẹ pe bi odundun ni igba tirẹ ma ntutu: ẹnikẹni ti o ba si șakiyesi ohun ti a sọ yi. le jẹri si pe ọmọ l'ẹhin Ọmọ-a'ade Alafia ati Ọmọ-lẹhin Onișẹ-nla pāpā ni Ọgbẹni wa na, o si jẹ ẹru Ọlọrun.

Ki ișe akoko leyi ti a ma nfi Ọlola yi de'le, kosi si igba to ma de'le ti a ko ni ri isami rere rẹ lara ilu, pe ki saba ma nsi Tẹmbẹlẹkun, tabi Ajinni-l'ẹsẹ ati Agbọyi-sọyi lọdọ Ijọba.

Ẹnyin enia wa yio șakiyesi oșu *October* ọdun kẹta ọhun (1921) nigbati awọn Kiriyo Onișokoto gbọrọ kan jẹ kunmoyo tan, ti awọn ndaba pe ki a wa Eleko Ọba wa, Herbert Macaulay, Kiniun Onibudo, ori-mayakiri agbojo lọwọ iku a-bẹru-Ọba-ma-bẹru-ẹnikan, Ọgbẹni J. Egerton Shyngle Kiniun Kotu, Oluwa Oloye Amolara bi iyawo ati awọn àgbàgbà Janma Musulumi Eko diẹ danu. Ẹ o șe iranti pe Oloye Sir Donaid Cameron yi kanna to wa ni Adele fun Ọba nigbana, lo fọ itẹgun ọ̀tẹ̀ yi tūtu ti o si t'ẹdi awọn alașeju bọ omi gbigbo-nà bi ẹni ki Ọba Gbadebọ (kabiyesi) tobẹ ti gbogbo rẹ fi tù, to si fi bà, a ko si le gbagbe iwa pẹsẹ Ọgbẹni na borọ. Ewo ko to tun nini Owe ba-nta-ba-nta [illegible] yi :—Ọba o s'eruku d'ẹgan, ati Ọba o s'ẹgan d'eruku: igba ni gbogbo nkan, igba l'așọ, igba l'ẹwu; A w'aiye ma ni'gba dabi eșinșin ku s'oju ọti.

*Seriki Goma Somoni Goma* gẹgẹbi ede Hausa, ti itumọ rẹ lọ bayi pe: Ọba mẹwa igba mẹwa, eyiti o wu ki lo o șe, ki Baba ma șai fun wa ni igba rere: Așẹ.

A ba Adele Ọba yọ si ori're rẹ yi, a si tun ba ara wa ati Ilu yọ pẹlu fun ẹ̀dọ̀ ti olukuluku r'aye fi s'oʼi orōro diẹ lasiko yi. Bẹ̃ tẹ̀ ni k'a ma ri o!!!

---

## IBÕSI OWO!

[*Lati ọwọ* ATARI AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji!

Owo jẹ alumọni pataki ti gbogbo Ẹda nja ijaka-di lati ni lọwo, bi ko ba si owo, kini a ba fi d'arà, ti ko ba si si àrà, kini a ba f' owo șe.

Ẹniti o ni bùkátà lati gbọ fun ara rẹ ati lori awọn ẹlomiran pẹlu ti Ọlọrun da ẹru wọn si agbe-da rẹ, ti ko si ni kọbọ kan lowọ, ibanujẹ șile ti s oluwarẹ di oku, la-lai ti i re 'tẹ Odumare 'ko fun wa l'owo ti yio șe wa ni anfani, owo tutu, ajẹmonu owo.

Oniruru ọna ni a fi nwa owo lode aiye, ẹniti o șu ọ̀șùka le'ri to nru ẹru ẹlẹru kiri ni aruwọrun, owo lo nwa; ẹniti ilẹ ko mọ ba lori ẹni, t'ojo t'ẹrun, șọ̀șọ́ o di ibi ișẹ, owo lo nwa; ẹniti o se onjẹ tan nile ara rẹ, to nkigbe "Ẹ o w'oju ọbẹ ẹ mu 'yan" kiri ilu, owo lo nwa; ẹniti o nfi ojojọ jẹ fẹsẹlù, owo lo nwa; gbogbo Oyinbo ati onișẹ ọba ati oni-șowo ati Oyinbo Kọrā to nbẹ ni ilẹ yi, owo ni nwọn nwa, bẹ gẹgẹ si ni awọn Kurumọ, Aganyin, Hausa, Ijọ ati Isobo ti nwọn fi Ilu wọn silẹ wa si ilẹ ajeji nibi nwa owo pẹlu.

Loya yi le sọrọ, ojojumọ lo nhan iyagbẹ bi ibaka ni kōtu, owo lo njẹ bẹ; Dokita nkọ, Sọfiọ nkọ, ọrọ gbogbo wọn lori Șile ha kọ?

Afa Șọși yi, Ajisọdidun ni, o mọ ọ nfitọ, șugbọn o ha jẹ sọ fun Ijọ rẹ l'ọfẹ laitẹwọ owo nipari oșu? Owo! Owo!! Bẹni Atari Ajanaku wi, gbogbo rẹ, owo ni!!!

...ṣe bi iru eyi lọna to tọ suna nitori ati l'owo ...o lodi si ofin, ṣugbọn ẹniti o nṣe owo erú, *Counterfeit Coin*, ni ireti ati di Sọnnu Meikudi nrin ni eti bebe ẹkun ori òṣì to le ta a ni atapa.

Ni lọlọyi ni a fi ẹsùn owo ṣiṣe sun awọn kan ti Ijọba ba ro ẹjọ ti nwọn si da lebi ẹwọn lẹhin na Ọgbẹni Koji Labelu jẹ ọkan ninu awọn ti konko ẹwọn rù, ani ẹwọn ọdun mẹjọ; anu rẹ si ṣe wa gidigidi. Ara oke ọmọ ọdọ rẹ ni ọwọ kọkọ tẹ, ṣugbọn gẹgẹ bi ẹjọ ti ọmọde yi rò ni Kōtu, ẹjọ Labelu papa ati eyiti meji tabi mẹta ninu awọn ẹlẹri rẹ rò, a tanma pe to ba jẹ pe Juri mejila l'ẹnu si ọrọ nā ni, boya iba ṣe nwọn l'oju su u diẹ, nitori gẹgẹbi a ti gbo, loju awọn Kiniun Loya Shyngle ati Thompson to ṣe ẹjọ na, ko si ẹri ofin pataki ti a le fi da Labelu lẹbi owo èrú ṣiṣe. *There is no evidence to convict the accused for making Counterfeit Coin.* Iyoku di Kōtu onidajọ mẹta, *Appeal Court.*

A fi ọrọ ti Koji Labelu silẹ. Ki tilẹ ni ero awọn ti o nṣe owo? Boya nwọn ro wipe bi enia ba le ṣiṣẹ nitori owo, ti o le ra ọja tita nitori ere owo, ti o le fi ile haya nitori owo: bi oluwarẹ ba kuku ṣe owo papa nkọ, ṣe o nran Ijọba lọwọ ni lati tubọ jẹ ki owo pọ ni Ilu, ewo li o kan ọran ẹwọn nibẹ? Ero ole, ero igara ni eyi; ẹniti o nṣe owo eru le sọ gbogbo owo Banki di oku, o si le run gbogbo Ilu patapata li arin oṣu mẹfa lai yin ibọn.

Nitorina, a fi Anọbi bẹ gbogbo ẹniti o nṣe owo-eru li Eko, li Abẹokuta, ni Ijẹbu, ni Badagry ati awọn Igara Ilu miran ti owo Ọba koi tẹ, ki nwọn ronupiwada—Ẹwọn ogun ọdun pẹlu ilagba mẹdọ-...ọn ni ibara idi kuro ni kekere iya.

Iba tilẹ ṣe wipe kiki awọn ti o nru ofin owo ṣiṣe nikan li o ma ji'ya ni, ṣe iba dun-dun; ṣugbọn wahala ti nwọn le gbe ẹlomiran ti ko mọ ọwọ, ti ko mọ ẹsẹ si nkọ nipa nina owo buruku fun wọn?

Boya Sanusi jẹ Salami ni gbese adọta pọnwun. Sanusi nṣe owo, Salami ko mọ. Nigbati akoko to lati ṣika alukawani, ¡Salami mu ogoji pọnwun owo daradara pẹlu pọnwun mẹwa owo aramu, o da a pọ, o gbe e fun Salami. Salami ka owo, owo pe; o ha le ma gbe adọta pọnwun lu'lẹ wo ni ṣile kọkan lati mọ bi o dun tabi ko dun daradara: Lẹhin ti Salami jẹri owo tan, o fi pọnwun kan pẹlu ṣile metala nibẹ ra apoti akara gbọkankan; Oyinbo ṣẹṣi ri ṣile meji nibẹ owo èru, o mu ọmọ Salami fun ọlọpa, rẹ-rẹ o di ile ọga rẹ; ọlọpa mu de 'bẹ, nwọn ba poun mẹwa o din ṣile meji owo èru, nwọn rá Salami mu, olobo ta Sanusi to na owo buruku yi fun u, gbogbo eyi to ku ni 'le rẹ ati iru iṣẹ to fi nṣe e, wonṣaṣa, o di inu ọsa. Salami ko mọ; o ni ki ọlọpa ṣe on jẹjẹ, o ni Sanusi lo fi owo na san gbese rẹ fun on, ọlọpa ba lọ si ile Salami, nwọn tu gbogbo ile, wọn ko ri nkankan nibẹ; Salami fi ake kọ 'ri, o gbe aṣẹ rù, o ta ko Salami wọnle, njẹ mo bere, ọṣẹ wo ni Salami le fi wẹ, to le mọ laijẹbi ẹwọn fun ẹṣẹ ti ko ni ọwọ, ti ko m' ẹṣẹ?

Nitori agbako yi ti o le ba alaiṣẹ, ẹnikẹni to ba ko firi ẹniti o nṣe owo, ki o maṣe jafara lati tete sọ fun Ijọba, ki o si fi eti Ọgbẹni Reis ati Ọpẹnibo ba irohin na

Nwọn ni bi a ba le akátá lọ tan, ki a dẹhin bọ wa ba adiẹ. Lakoko ti Kọrẹnsi ko si, ti ko si si owo pupa ràkọràkọ bi apadi iru eyiti a nlo nisisiyi bikoṣe fadaka faufau, enia diẹ nṣe owo èrú nitotọ, ṣugbọn pẹlu irọrun ni a fi nmọ iyatọ larin owo èrú ati ti fadaka nigbana; nisisiyi, o ṣoro pupọ lati mọ ọkan yatọ si ekeji, nitori owo ti Ijọba papa nlo fun wa ni Ilu, ko dara to rara—ṣile kan rẹ ko tilẹ l'ẹwa to kọbọ aladọjọ pupa lailai.

Adẹhinbọ ogun ajakaiye to ko Kọrẹnsi wọ Ilu lo ko owo pupa bi idarọ wa, ati lati fi ifẹ (*loyalty*) ati anu (*sympathy*) wa han fun Ijọba Gẹsi labẹ abo asia ẹniti a wa pẹlu inu didun, bi o tilẹ jẹ pe iyẹpẹ ni nwọn nna fun wa gẹgẹ bi owo lakoko idamu ati wahala ogun nla Jamani, sẹria gba iyẹpẹ na dipo owo.

Idi ọrọ re o, aladugbo, ti a ṣe nfi Epo, Cocoa, Ekurọ ati Obi wa gba Kọrẹnsi, iwe lasan lasan ti ko ni lari—*a paper of no intrinsic value*—lakoko na, tayọtayọ laisi ikunsinu.

A ha le sọ iye kọrẹnsi ti ekute jẹ, eyiti omi bajẹ, eyi to jona, eyi to faya, eyiti o sọnu lorişirişi ọna; ani, a ha le sọ iye oja ti kọrẹnsi sọ di ọwọn tabi iye enia to sọ di onigbese larin wa? Nigbati ogun pari, ti inira si pọ fun wa, ikorira de si kọrẹnsi, gbogbo wa nki gbe owo, owo; a ko mọ pe nigbati Ijọba ba bẹrẹsi gbe aja ta, ọbọ lo ma fi ra fun wa.

A ko fẹ hùnrẹn buruku ti Ijọba npe ni owo fun wa yi mọ, o to gẹ ẹ. Ko si aiyederu ninu iṣẹ ti a nṣe fun Ijọba, ko si aiyederu ninu gbogbo ọja ti a nta fun Oyinbo onişowo, ko si yẹ, ẹwẹ, ki aiyederu wà ninu owo ti nwọn nfun wa.

Ọrọ ija kọ, ọrọ ipa kọ, ọrọ ẹbẹ ni. Nitorina, a bẹ Ijọba pupọ ko f' eti si aroye wa, ki o ko owo buruku kuro larin wa, ko si fi fadaka ati iwòro to jire dipo wọn fun wa. Ẹniti ko ba fi ilá tan ni jẹ, a ko nfi ibo tan a jẹ.

Emi ni ti nyin nitotọ,

**ATARI AJANAKU.**

## "EMPIRE DAY" NI BADAGRY.

Si oniwe "Eko Akete",

Inu mi yio o dun bi o ba le fi iwe irohin kekere yi si apakan iwe rẹ.

Pagidari, irohin ko to afojuba, ẹnyin ọrẹ ti ẹ lọ si Badagry ni ọjọ Jimọ ọsẹ to koja (23/5/24.) lati lọ ba alabojuto ilu (Capt: J. H. Balfour de Montmorency) ati awọn ara ilu ṣe ariya "Empire Day" ẹ ku abọ, ṣugbọn a ni lati dupẹ lọpọlọpọ lọwọ akọwe Ẹgbẹ ariya na, Ẹbun: Adeniji fun orişirişi eto ti o ṣe, a ko gbodọ ma sọ pe o jẹ nkan iyanu fun wa pe a ko ri ninu ọmọibilẹ Badagry ti o duro ti akowe yi lati ran lọwọ rara fun eto kan, on nikan ṣoṣo na ni a nri fa sọtun ati si osi fun ohunkohun—igi ma da o; ko kuku si bọkini kan ti oju rẹ la lati ṣe iranlọwọ ni!! abi kilo tiri? A bi a ko ni ọdọmọkunrin ti o ja fafa to lati ran lọwọ ni, ṣugbọn kini Mr. Y. Balogun ṣe, a mọ daju pe o ti wa ni Eko fun ọdun mẹlo kan, oju rẹ si mọ diẹ lati mọ eyi ti o tọ lati ṣe, abi Isọgbetọ, to wa jo ni ọdan ni ọjọ na ti o mba sare kiri lo gba lọkan tobẹ, eyi ko dara, ki o ṣe giri, ki o mura lati ran akọwe yin lọwọ daradara ni odun to mbọ, bi Ọlọrun ba pa wa mọ di akoko na—Mo dupẹ pupọ lọwọ Ẹbun: Adeniji ti ko jẹ ki awọn ọrẹ ti o wa lati Eko ri lala kan fun atijẹ ati atimu wọn titi wọn fi pada wa si Eko. Mo si dupẹ lọwọ Mrs. Williams, Akuruyẹjo obinrin fun ariya ati gbigba to gba wa tọwọ tẹsẹ nigbati a de ile rẹ. Mo dupẹ lọwọ Baba Ẹgbẹ igbimọ ariya yi, Ọgagun Montmorency fun ayan rẹ ni ilu na, ati lọwọ awọn igbimọ ariya yi, papa lọwọ awọn Bọkini Ṣobọ, Padonu, Cadmus ati awọn to ku, fun inawo wọn. Ṣugbọn nko jẹ ma sọ pe awọn igbimo ariya yi ko mọ riri enia, ti o ba jẹ pe wọn mọ riri enia ni, wọn ni lati wa bẹ awọn ọrẹ ti o jẹ pe a pe lati Eko wa ba wọn ṣe ariya wo, bi o ṣe ẹkan ṣoṣo ni ki wọn to pada bọ wa si ile wọn—Ṣugbọn wọn ko wa wo ni rara, eyi jẹ nkan abuku, abi ko ye wọn debẹ ni? Ẹ sọ fun wa.

Ni owurọ *Saturday* ni nkan agogo mọkanla ati abọ ojo rọ titi di nkan agogo mẹrin ṣugbọn nigbati ojo yi da ni a lọ si Ọdan lati lọ wo awọn ọmọ ile iwe ibẹ fun ere ti wọn ni lati ṣe, Ere na dun pupọ, wọn sare ẹlẹsẹ, wọn fogi, wọn ko sinu apo, Ijakadi pọnrọnyin ni, a si fi ẹṣin sare nibẹ, Mr. Fanu, Mr. Kasumu fi Eko silẹ lọ fi Ẹṣin sare ni Badagry pẹlu oloko ẹṣin, lọgan, oloko ẹṣin judi fun wọn, o gba ere ije na, yegede!!

Ni alẹ ni a lọ si apejẹ ti Ọgagun Montmorency pe awọn Sọmọri ni ilu ati awọn Bọkini ti o wa lati Eko si, orişirişi awo onjẹ ni o palaṣẹ fun awọn ọmọ ọdọ rẹ pe ki wọn gbe wa si tabili-ikan ko jọkan ni, lẹhin onjẹ ni Ọgbẹni Benka-Coker sọrọ, Ọgagun Montmorency si gbe lẹsẹ o si dupẹ lọwọ rẹ ati awọn ara Eko ti wọn wa ni tabili pẹlu rẹ ati awọn ara ilu na pẹlu, lẹhin eyi a tuka kuro ni tabili fun ijo. O jẹ nkan to yani lẹnu pupọ pe bi ilu na ti to, a ko ri omidan kan ti oju ... lati wa si ibi ariya, ọpẹlọpẹ Mrs. Williams on lari, awọn ti a tun ti ba jẹ ara ilu to wa w..., A dupẹ lowọ Macaulay, Fanu, Pedro ati Kasumu to mu obinrin bọ ni lọ, egun kan egun ni ijo ti gbogbo wa iba jo) ki a to tuka eyi ku diẹ ki o to, ẹnyin ara Badagry nigbati o jẹ pe ilu yin ni Oyinbo kọ de, sibẹ afari kodoro ni ẹ şi jẹ. Ẹ mura fun ọdun to mbọ ki ẹ ba le ṣe ju eyi lọ, nko ba nyin wi rara, ọrọ lo lọ bẹ. Ki ẹ si dupẹ lọwọ Ẹbun Adeniji fun ayan, ati lala rẹ lati la yin loju si.

Ọgagun J. H. Balfour de Montmorency, alabojuto ilu fun awọn kan ni ẹbun, ninu awọn wọnyi, ni Rẹmi Taylor, awẹlẹwa obinrin, ẹlẹyinju ẹgẹ ati J. Ade. Ogunbiyi ẹniti o ba jo gba ẹbun fun ẹwa, ati imọ toto, Ẹbun Adeniji, gba ẹbun pẹlu fun aṣọ meremere, alarabara to wọ, Ẹwu eşu to pupa fọ fi ododo ti o si ni iyẹ lapa, awọn miran si gba ẹbun pẹlu.

Tani pa ọrẹ wa Mr. S. lẹkun ninu ọkọ?<br>
Eku Ẹda ni!<br>
Nitori kini—<br>
Nitori Ṣẹkẹtẹ Oyinbo (*Beer*)

Ẹ ba ni kilo fun Eku Ẹda ki o ma mu suru diẹ ninu ohun gbogbo, ko mama sọ pe ọrẹ mu *Beer* (Ṣẹkẹtẹ Oyinbo.) Eyi ku diẹ ki o to, ọrẹ wa le ra apoti Ṣẹkẹtẹ Oyinbo fun alejo, ki iṣe ongbẹ *Beer* ni o, ngo gbe Eku Ẹda, agba di ọwọ rẹ.

Emi ni tirẹ,

AKEBIORO.

## NI IRANTI.

Ni Iranti Ifẹ ati ibanujẹ Ọrẹ mi ọ̀wọ̀n

Ẹni-Ọwọ S. M. ABIỌDUN, M.A., L.TH.,

ẹniti o bọ ara amọ yi silẹ ti o si gbe aiku wọ ni oru ọ́gbọ́n ọjọ oşu *May*, 1923, ni Eko.

"Enia ti a bi ninu obinrin, ọjọ kukuru ṣa li o ni igbe li aiye, o si kun fun oşi. O ndagba soke, a si ke e lulẹ bi itanna eweko; o rekọja lọ bi ojiji!!"

"Nihin li awa njẹ irora,<br>
Nihin ni awa npinya;<br>
Li ọrun ko si ipinya.<br>
A! bi yio ti dun to<br>
Nigbati a ki yio pinya mọ!<br>
Abiọdun, o bọ lọwọ aiye ati ẹṣẹ."

Baba, labẹ itọju Rẹ li awa fi Iranşẹ Rẹ yi si titi ọjọ ajinde ti o logo—Amin.

E. J. AJAYI.




# ERVEN LUCAS BOLS

## AMSTERDAM

**1575**

---

Whenever you see the word Bols it means a reputation of over 300 years.

***Bols very old LIQUEUR GIN is the Gin for the man of good taste.***

## STONE JARS AND GLASS JARS

## **5s.** per Bottle

***FROM***

# GRACE BROS.

***— DRINK IT NEAT. —***

## *Preachers for To-morrow.*

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

Time. Preacher.
9 a.m. Christ Church, Bishop of Lagos (in Charge)
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. Paul's (Breadfruit) Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi
6.30p.m. do. do.
9 a.m. St. John's (Aroloya) Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. Peter's (Alapako) Rev. S. V. Latunde
6.30 p.m. do.
9 a.m. Holy Trinity (Ebute-Ero) Rev. S. J. Gansallo
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. David's (Jordan)
6.30 p.m. do.

**WESLAYAN**

10.30 a.m. Tinubu Rev. A. N. Cole
7 p.m. do. D. A. Bababumi
10.30 a.m. Ereko Rev. M. N. Q. Sagoe
7 p.m. do. do.
10.30 a.m. Olowogbowo Rev. E. E. Williams
7 p.m. do. Rev. A. N. Cole
10.30 a.m. Ọbun Eko Rev. H. W. Stacey
7 p.m. do Rev. S. A. Pearse.

**AFRICAN (COMMUNION)**

9 a.m. Jehovah Shalom Rev J. F. Ogunko
7 p.m. do. Rev. Supd G. A. Oke
9 a.m. Erelu do.
7 p.m. do. Bro. J. A. Laleyẹ
9 a.m. Christ Church (Ebute Mẹta) Bro. J. A. Laleyẹ
6.30. p.m. do. Rev. J. F. Ogunko
9 a.m. Bethel Rev. E. A. Akinọla
6.30 p.m. do. do.
6 a.m. Zion Rev. N. J. D. Ṣomuji.
6.30 p.m. do.
9 a.m. Salem Church (Ebute Mẹta) Rev. J. A. Wright
6.30 p.m. do. Bro E. O. Peters
9. a.m. Bethlehem Church (Ebute Mẹta) Rev. E. D. Ṣhodẹinde
4. p.m. do. Bro. E. A. Delala

10.30 a.m. African Methodist Rev. I. [illegible]oju
4.30 p.m. do. Bro. J. O. Williams

**FIRST BAPTIST CHURCH**

10.30 a.m. Bro. M. O. Fadipẹ
6.30 p.m. Rev. J. R. Williams
9 a.m. Ararọmi (Baptist) Bro. E. A. Ojo
6 p.m. Rev. A. A. Puddicombe

**EBENEZER (BAPTIST)**

9 a.m. Rev. E. C. Alabi
6.30 p.m. do.

**BROTHERHOOD**

7.30 a.m. The Founder
7 p.m. do.

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM.)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.)

**ZION CONGREGATIONAL.**

9 a.m. Kakawa St. Rev. Supt. S. A. Coker.
4 p.m. do. do.

**SALVATION ARMY.**

10 a.m. Glover Memorial Hall Capt. A. A. da Costa
7 p.m. do. Lt. Col. Geo. H. Souter

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. F. Terrell

## IGBẸ L' OWO WÀ.

Bi awọn Oyinbo Oniṣowo ilẹ yi ti gba awọn Ọja wọnyi si l'oṣẹ yi ni eyi:—

EKURỌ

£14 4 0—£14 10 0 fun *ton* kan.

EPO.

£24—£26 0 0 fun *ton* kan.

COCOA.

£16 0 0—£18 10 0 fun *ton* kan.

**KANO.**

EPA.

£12 0 0 fun *ton* kọkan.

AWỌ (*Skins and Hides.*)

Skins 1/9d fun lb kọkan.
Hides 5d fun lb kọkan.

# Lever Stores Ltd.

# OLOWO S'OKE D'ILẸ

## No. 1, LAGOS.

A ma nṣi Ṣabu wa di agogo kan ọsọsan Thursday.

A si ma nti ilẹkun ni agogo meje alalẹ Saturday.

A nta ọja wa ni Tọrọ, Sisi, Nain ati Ṣile kan pere.

Ọpọku-ọyọku si ni owo wọn.

ILE-ÒWÒ OYINBO ALALUMỌGAJI.

# John Holt

NI OJA WỌNYI FUN TITA

Sarotu "Alasia"

Keke-ologere ( Elerin )

Keke-Ologere ( *Rudge Whit-Worth* )

Panu Iborule

Awo

Awo=abomafo

Eja-abomafo

Iyefun

Sulfuri

Efun

Alum

Oda-dudu

Orisirisi Oda-ikunle

Iso

Panu-kiko'le

Isana ( Atuko )

Ẹ bere ni Ṣabu **JOHN HOLT** ni, Opopo-nla, ni Eko.

"*Ebani*" ni ede-waya ti ẹnikẹni le lẹ si wọn nibikibi ni Ekọ tabi ni Ilu miran ni *Nigeria*.

## EMPIRE DAY AT BADAGRY.

On the invitation of Mrs. Baxendale on behalf of a Committee of Gentlemen a grand Picnic was given at Badagry to friends from Lagos on Empire Day. The Invitees left Lagos by the French Boat *Faadji* at 6 p.m. on Friday the 23rd May. An enjoyable evening was spent on board by dancing to the strain of Horquart's Orchestral Band specially engaged for the occasion. It is necessary to connect the names of Messrs. Verdin and Mathews with the evening's success, as they contributed largely to made it so. This happy enjoyment was broken at 12 midnight when the boat reached Badagry.

The thanks of the Picnic Party were due to the undefatigable efforts of Mr. H Macaulay of H. S Macaulay & Co. of Badagry, who arranged with the Monsignor Faux, the kind Agent of the French Company, to permit the *Faadji* to go along side the African Oil Nuts Wharf. The party was met by the energetic Secretary of the Committee, Mr. S. Ebun : Adeniji, District Officer's Chief Clerk at the landing stage. The party were lodged at the Fest House where every comfort that could be desired was provided. Coffee was served and the party indulged in dancing and games until 5 a.m.

According to the Programme for Saturday the 24th at 7 a.m. the party started in procession for the premises of Messrs. African Oil Nuts where Tennis was played till 9 a.m. when the sun rays made it impossible to continue. The party retired to the Fest House and a sumptuous breakfast was served.

Unfortunately at about 12.30 p.m. there was a heavy rain which at first seemed to mar the progress of the day, but at about 3 p.m. the weather gave promise of a lovely evening; the school boys were formed in order of their schools at the Court Hall. The District Officer, Captain J. H. Balfour de Montmorency supported by Mr. and Mrs. Baxendale, Agent of Messrs. Miller Brothers, H. J. Verdin, Agent of Messrs. African Oil Nuts, and Mr. J. P. Mathews of the MacIver presided. Addressing the School children, he spoke impressively pointing out to the children their duties towards the British Empire. His Address was interpreted to the children by Mr. S. Ebun Adeniji. The weather being fair the children left the Court Hall for the Fields to engage in sports. The conduct of the sports under the management of the District Officer and his Supporters shewed that they are really sportsmen. Among those present at the sports mention may be made of the following.—Chief Jengen, Chief Aminu, Chief Akaran, Chief Toyi, Yesufu the Balogun, Iroko Zonu, Bale of Igbososan, Bale of Ibiku, &c., and Mr. Benka-Coker of the Southern Secretariat, who acted as Master of Ceremonies. After the close of the sports Mrs. Baxendale kindly distributed Prizes to the Winners. Special Prizes awarded by Mr. Baxendale for Wrestling &c. were also distributed.

To bring the Programme to an end the Flowers of Badagry and the Party from Lagos dined with the District Officer. The dishes served left nothing to be desired. Drinks were profusely served, while Horquart's Band was discussing lovely music at intervals. After dinner the Toast of the King was proposed by the District Officer and heartily drunk. The next Toast which was that of the President of the Committee, Captain Montemorency was proposed in glowing terms by Mr. A. Benka-Coker. The District Officer, Mr. Coker said, is beloved by the whole people in the country from his observation both old and young, and he hoped that such lovely spirit that exists between the European and the African Elements will continue for the progress and elevation of the Colony of Badagry. This toast having been proposed was also drunk heartily.

( *To be continued.* )

# H. S. Freeman

hotographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.)

ealer in all kinds of Photographic Materials

Films, Post Cards, Views etc., etc, on hand.

"Also films undertaken for development."

Satisfaction Guaranteed.

*Office* :—106, Tokunbọ Street, Lagos.

*legraphic address* :—"FREEDE" LAGOS.

P. O. Box 495.



## ILE OWO KADUNA

mbẹ lẹgbẹ Ile-afin Ọgbẹni A. W. Thomas ni 75 ati 81, Ita Odunfa, (Anikantamọ) L'Eko.

Awa ni orişirişi Kẹkẹ-ologere ati Kẹkẹ upu-pupu ni tita, a si ni awọn "Ero-ija" ọn pẹlu.

Lati ọdun 1921 l' a ti wa lẹnu işẹ yi, wọn ọja wa si to ọja o ni igba pọun £200.) Ko si bi Kẹkẹ-ologere kan tabi pupu-pupu kan ti le bajẹ to ki a ma be'ro: a si nra awọn "oku" Kẹkẹ-logere, oni-pupu-pupu, ati Ẹrọ-akọrin (*Gramophone*) ti a ntun şe ti a si tun nta owo pọ̃, bi £3, £4, £6 10 fun awọn ọniti ko ba to pẹmu olowo-nla ru.

Ẹ wa tabi ẹ kọwe şọwọ si Olotu Ile-owo yi :—Ọgbẹni Sam Ade Clay ni adugbo ta darukọ loke yi, tabi ni No. 1, Ita Macaulay (Okepopo) l'Eko. Owo lọwọ ni gbogbo Ọja rẹ o, aibamọ.



Mr. Sam O. Amọdu, Apẹlẹhin ti Igbobi nwo awọn aisan wọnyi san :—Warapa, Akọ-oyi, Were, Arun-aşiri, Ẹsọ Asunkun, Oke ilẹ, Ajilẹ, Ẹsẹ, Lakuregbe, Asıngun, Ẹda, o ni agumun fun Inarun, Iba, Tulu, Aran orişirişi, Aiperi, Ipa, Latanlatan ati onirunru arun miran.

Ẹ lọ dan wo.






*4/6 each.*

## The Kaduna Store,

75 & 81, ODUNFA STREET,

*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence.*

ẸBUN HOUSE, Lagos.

begs to inform all Cyclists and Motorists to *buy* always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc.

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our Store, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz :—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor :—

SAM ADE : CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

Terms :—Cash with Orders.



## AGA, AGA, AGA

FUN YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.

OWO PỌKU NI A FI NYA NI NISISIYI, (1½d.) KỌBỌ KAN PẸLU ABỌ.

Lọ si ọdọ Alabojuto,

Ọgbẹni J. A. OSHODI,

No. 26, Ita Ọbun-Eko.

LI EKO.

# A. Kessler,

7, Labinjo Lane,

Williams Street,

**P.O. Box 459**



THE

# Pilsener Beer

*Lion Brand*

*Light & Sparkling*

Per Case

34s.

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe ile ẹ oṣo. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a li ẹbi iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati Efa, ti iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti o fi ọwọ mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Ọṣẹ Olọwọ—agaga; Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o ba fẹ ẹ ni *tọnu* a le ta a fun o, Iṣana Alapoti fun tita, ko si bi a ti nṣe wọn. Oriṣiriṣi ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma jere tirẹ, nitori owo pọku ni a nta wọn. Owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja irọ wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan; 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kọwe sọwọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMBẸ & BROS,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
(*Lẹgbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangalakis*),
Idumagbo, Eko.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi oriṣiriṣi Egbogi lo ṣẹṣẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo oriṣiriṣi, ogun Ẹ̀da, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran oriṣiriṣi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.